# IROHIN IMOLẸ

IMOLẸ ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

No 1,576 FRIDAY DECEMBER 3, 1965 (2D)


## Okunrin Kan Jabo Lati Ori Igi Obi

ABẸOKUTA:- Jinnijinni dabo gbogbo enia nigbati ariwo ta gee ni abule kan ti nwọn npe ni Alapo Aro ilu kan Lẹba Abẹokuta pe ọkunrin agbẹ kan Joseph Kadiri jabọ lati oke igi obi kan o si ku u lẹsẹkẹsẹ ti okurin agbẹ na jabọ lati oke obi na ni ọjọ Isẹgun ti ise ọgbọnjọ osu to kọja lọ yi

Irohin lati ọwọ awọn ọlọpa ti ilu Abẹokuta fi ye wa pe ninu oko kan ti nwon npe ni Bereọla ni nwọn ti gba ọkunrin na gẹgẹbi Lebira lati lọ ba wọn ka obi eyiti o jẹ wipe bi ọkunrin na ti gun igi obi na ti o bẹrẹsi ni ka obi silẹ ni o ba jabọ lojiji eyiti o jẹ wipe lẹsẹkẹsẹ ti ọkunrin agbẹ na ti jabọ lati oke igi obi na lo si ku.

Irohin awọn ọlọpa tun fi ye wa pe nigbati awọn ẹbi ọkunrin na ri pe ko ti de lati oko ibiti o ti lọ ka obi na ni awọn enia na ba bẹrẹsi ni ṣe iwadi ibiti ọkunrin agbẹ na lọ.

Ko si pẹ pupọ na ni awọn ẹbi ọkunagbẹ na ba bẹrẹsi ni wa oko kakiri lati ma wa ibiti ọkunrin na lọ eyiti o jẹ wipe awọn enia na ri oku ọkunrin na ni abẹ igi obi kan eyiti o jẹ wipe o ti ku patapata. Nwọn si ti gbe oku ọkunrin na lọ si ile Iwosan ti ilu Abẹokuta lati lọ ṣe ayẹwo rẹ.

# AWỌN KAN TUN DANA SUN ENIA MEJI LAAYE !

ILISHAN:- "Kaka ki o san lara iya ajẹ o fi ọmọ rẹ bi obinrin ẹiyẹ nyi l'eiyẹ" ni ohunti o nṣẹlẹ ni jakejade Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria jẹ nipa abayọri idibo si ile Igbimọ Asofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria eyiti ọpọlọpọ ẹmi si ti padanu lori rogbodiyan to nṣẹlẹ ni Ipinlẹ na ati paapa julọ lori okẹ aimoye awọn ile ti nwọn ti dara sun ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria bayi.

Ninu irohin to de ile iṣẹ wa ni owurọ ọjọ Iṣẹgun ti iṣẹ ọgbọnjọ oṣu to kọja yi ni ati gbọ wipe ile ti nwon ti dara sun ni ilu Ilishan ati Ikẹnnẹ ni ẹkun Ijẹbu-Rẹmọ bayi jẹ mẹtale logun ni oru ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kejidinlogbọn oṣu to kọja yi ni iṣẹlẹ na si ṣẹlẹ

Bakanna ni enia mẹta merin si tun padanu ẹmi wọn lori ohunti o nṣẹlẹ ninu awon ilu meji na. Ni ilu Ikẹnnẹ ni awon enia kan ti yin ibon pa awon omo ẹgbẹ Afẹnifẹre meji ti awon omo kunrin meji na tun jẹ omo ilu Ilishan ati pe ni ilu Ilishan ni awon enia kan ti dana sun awon enia meji ninu ile kan eyiti o jẹ pe awon enia meji na si jẹ Obinrin.

Ohunti o fa iṣẹlẹ nla na wa ni asikoti awon enia ilu Ilishan gbele gbo irohin pe awon enia kan ti yin ibon pa awon omo ilu na meji ni osan ojo Aiku ti iṣe ojo kejidinlogbon oṣu to koja lo yi ni ilu Ikẹnnẹ.

Irohin tun fi ye wa pe lẹsẹ kanna ni awon enia ilu na ti bẹrẹsi ni ba opolopo ile jẹ ti nwon si nba awon ẹgbẹ oṣelu ti o jẹ alatako wọn ja eyiti o fi jẹ wipe olu kuluku si bẹrẹsi ni yin ibon ni opopo ilu na.

Bi awon enia wonyi ti bẹresi yin ibon ni awon enia kan lo ti ilekun mọ awon obinrin meji kan ninu ile won ti nwon si dana sun ile ti awon obinrin na wa eyiti awon obinrin na fi jona rau ru s'inu ile 'lawye

Ni ilu Ikẹnnẹ ni awon enia na ti dana sun ile iṣe ijoba ibile ilu na ti won tun dana sun gbogan ilu na eyi o je wipe gbogbo na lo sijo na patapata

Bakanna ni nwon tun nlo ada bi eni pe awon omode isire eyiti o je pe awon enia na tun ṣa asoju ile iṣẹ iwe ranṣẹ ti ilu Mushin Ọgbeni Dada eyiti nwon gbe lo si ile iwosan ti ilu Shaga lati lọ se itoju re

Bakanna ni awọn enia na tun ṣa awọn ẹlomiran lada ti nwon si gbe wọn lọ si ile iwosan ti ilu Sagamu lati lọ ṣe itọju wọn nibiti nwon ti sa wọn leda ṣugbon ẹmi awon enia na ni a gbọ wipe o wa ninu ewu ni ile iwosan na bayi

Bakanna ni awọn enia kan tun yin ibọn si oloriẹgbẹ Dẹmọ ti ilu Ikẹnnẹ Ọshọ eyiti o jẹ wipe awọn ọlọpa si ti gbe lo si ile iwosan ti ilu Shagamu lati lọ se itọju rẹ

Ninu eniti awọn enia na tun dana sun ile rẹ ti o jo patapata ni Adajọ ti ile ẹjọ Ijọba ibilẹ ilu Ikẹnnẹ oloye Opẹaiye Oludọtun Irohin fi ye wa pe oloye Oludọtun ti sa kuro ni ilu Ikẹnnẹ bayi ati pe o ti sa lọ si ibiti ẹni kankan ko mọ ibiti o wa bayi

Ni ilu Iiesha ni onirohin wa ti fi ye wa pe gbogbo awọn ọna to kọja si ilu na ni awon enia ilu na ti gbe igi nla di oju ọna na eyiti o jẹ wipe ti awọn ọlọpa ba nbọ nwọn ki yio ri ọna gba lati kọja lọ si si ilu na

Gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ti wa ni ilu o ti a gbọ wipe nwọn ti sa kuro ni ilu na ti nwọn ti lọ sa pamọ sibi ti ko si eniti o mọ ibiti nwọn wa bayi

Oniwe irohin wa tun fi ye wa ninu awọn ilu meji ti iṣẹlẹ na ti nṣẹlẹ na ni a ti gbọ wipe rogbodiyan na ko ti lọ si opin rara ati pe ọpọlọpọ ile ni awọn enia tun ndana sun ni ilu mejeji na.

Nwọn si ti ko awọn Ọlọpa ati Ṣọja lọ si ilu mejeji na lati lọ ṣe eto gegebi eto alafia yio fi wa ninu ilu na bayi.

Oniwe irohin wa tun fi ye wa ninu irohin rẹ pe ọpọlọpọ awọn enia ti nwọn jẹ ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ti nwọn si ngbọ ohun ti o nṣẹlẹ yi lọ ti binu kuro ninu ẹgbẹ na ti nwọn si pada sinu ẹgbẹ Afẹnifẹre

## Nwọn Da'na Sun Moto !



MUSHIN:- Gbogbo ilu lo gbojikan fun ariwo ti awọn enia si bẹrẹsi sare olọmọgbẹmọpọn nigbati awọn enia kan ṣa ina si mọto KIA-KIA kan ni ọna Ikorodu Road lẹnulọlọyi ti awọn ọlọpa ati panapana si sare wa pa ina na,

Onirohin wa kan fi ye wa wipe, lati ọjọ ti nwọn ti di ibo tan sinu Ile Igbimọ Asofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kọkanla oṣu kẹwa ọdun yi ni rudurudu ti bẹrẹsi ṣẹlẹ yika gbogbo Ipinlẹ na.

Bi awọn enia ti nda ina si mọto awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ, bẹẹni nwọn tun nda ina si inu ile wọn pẹlu.

Irohin ti gbogbo awọn WO OJU EWE KẸFA

## Iwe si Olotu Irohin Imolẹ

### Ilu Ipokia Nfẹ Itoju Ijoba

Olotu Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin to kun fun ọgbọn ati oye lati kesi Ijoba Ipinlẹ Iwọ O r u n Naijiria lati tete ba awa enia ilu Ipokia mu oju to ilu wa ati paapa julọ awọn Oju ọna wa ti ko ba oju mu ati pe a si ofẹ awọn nkan miran ti yio mu ilọsiwaju si ilu wa nitori pe a ko mọ ohunti Ijọba fi Owo Ori ti a nsan ṣe.

Mo ro pe o ti to Ọdun melo seoin to jẹ wipe a ti nkesi Ijoba Ipinlẹ Iwo Orun Naijiria lati ṣe iranlowo yi fun wa ṣugbon ko si eto iranlowo kankan ti a ri gba lati igbati Ijoba na ti kuro lowo ẹgbẹ Afenifẹre ni ko ti si ohun idagbasoke kankan ni ilu wa.

Inu awa enia ilu na yio dun bi Ijoba Ipinlẹ Iwo Orun ba le ṣe awọn nkan wonyi fun awon bi Ile Iwosan nla, Ero omi, ina mọnamọna ti yio wa kakiri opopo oju ona ilu wa ati ile Ifi iwe ranṣẹ pẹlu

Olotu mo dupẹ pupọ fun aye ti e gba mi ajinde yio ma jẹ fun nyi i O

Emi ni
Bisi Alade
IPOKIA

### Alagba O di Owo Nyin O

Olotu Jowo gba mi ni aye diẹ ninu iwe rẹ ti nko wa ni ogbon ati oye lati kesi awon ti o jẹ omo Yoruba ki nwon lo ronu jinlẹ gidigidi ni asiko yi ki nwon lo ma fi ti awon Ipinlẹ toku kogbon.

Bi ija ba wa larin awon ẹgbẹ Oselu ni Ipinle iṣe ti o ye ki awon alagba Ipinle na ma ṣe ni pe, nwon npe won papọ nwon a si da ebi fun eniti o jebi lati are fun ẹniti o jare nigbana ẹniti o jẹbi yio tọrọ idarijin lọwọ ẹniti o jare

Ṣogbon ti awa Yoruba Yoruba yato patapata nipa ọgbọn madaru oju a maa ti wa lati da enia nla lẹbi l ju rẹ nipa siṣẹ bayi ao wa m.. pẹ ọrọ sọ ni ipari ao so pe, aw n mejeji ni o jare ko si bi ija na ti pari to ti ko tun ni jẹ jade mọ nitoripe lori m.da ru ni a gbe id.jọ le

Mo bẹ awon alagba ti o fẹ pari edeaiyede ti o ti wa nilẹ lati bi od.n meta ṣehin pe bi nwon ba fẹ p ri ija na patapata ti nwon da ebi fun elebi ati are fun alare ki nwọn si kilọ fun awọn alaṣeju

Emi ni
J A Ayanwale
IBADAN

### Ẹla Eyi Ye Mi

Yio je didun inu mi bi olotu ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe rẹ oloyin mọmọ lati bere ọrọ mi yi ni odọ awọn ti o ba tọsi nitoripe ọrọ na ko yẹ mi rara nitoripe ọrọ lori ibo yi da ohun ti ko dara silẹ eylti ko le tan nilẹ lailai mo bẹ awọn ti o wa idi eto na pe ki nwọn wa sọ ti ẹnu nwọn fun araiye gbọ.

Nigbati Ọlọla Fadahunsi Ọdẹlẹyẹ Gomina Ipinlẹ Iwo Orun ma sọrọ o ni gẹgẹbi iwe ti on ni gba lati ọwọ Olori eto ibo ti Ipinlẹ Iwọ Orun ni on fi yan Oloye Akintọlẹ gẹgebi Olotu Ipin le Iwọ Orun:

Nisisiyi Ọgbẹni Esua Olori eto Igbimọ ibo ti fesi pe on ko kọ iwe kankan si ọlọla Ọdẹlẹyẹ, Gomina Ipinlẹ Iwọ Orun lori ibo ti nwọn di ni ọjọ kọkanla oṣu kẹwa ọdun,

Nigbati a tun gbọ nwọn ni akọwe eto igbimọ ibo ti Ipinlẹ Iwọ Orun ni o kọ iwe ranṣẹ si Gomina ọrọ na ko yẹ mi rara mo fẹ ki Ọgbẹni Ọjẹrinọla tete sọ ti ẹnu rẹ nitoripe ori rẹ ni nwọn di gbogbo ọrọ na le lori

Olotu ajinde yio ma a jẹ O.

Emi ni,
Lajide Adeyanju
ILESHA.

### Iwo Ha Nfẹ Ile LEko Bi

| | |
|---|---|
| Room | £3 10/- |
| Room | £4 |
| Room | £5 |
| Room / Parlour | £6 |
| Room / Shop | £15 |
| Flat (Lagos) | £20 |
| Flat (E.B) | £25 |

Ti o ba nfẹ ọkan ninu awọn ile wọnyi yaa tete lọ r Ọgbẹni ODUSI — 187 Bamgboṣe Street Lagos. ni deede agogo merin irolẹ si agogo mẹfa irọlẹ. ijafara le.u anfani nla kan ni eyi jẹ fun ọ pe o ri ile l'Eko


### Angelina Super — Rose
(O TI LỌ WA JU)

Eleyi ṣeṣẹ jade ni ko si nita rara aṣeṣẹ jade akan a ko mọ ibiti o nlọ ohun pataki ti a mọ nipe "O ti lọ wa ju"

Super rose yi wa fun ipara gbogbo enia lọmọde Agba lọkunrin ati lobinrin o tun wa fun irun didi ati kiko olowu o nmu irun ọkunrin papọ ma dan ki o si jọlọ o ma fun ara ni ẹwa akotun awọ ara yio jẹ yọ jade perepere

Bi enia dudu ba loo yio mu da gẹgẹbi jigi enia pupa agaga ṣe iyen ti wa tẹlẹ.

Tere sare wa tabi ki o kọwe fun tire loni ki o to tan ni 'International Cosmetic Industries" 36' Ọmọwunmi Street, Ichin kansulu Mushin Ẹ tọju ara ati irun nyin ẹ tọ ju pelu awuje ọmọ nyin owo pọku ni 1/3d fun eyọ kan 15/- fun mejila wa fun alaye si.

### IWE KOṢEMANI NI EYI

IWE ITỌSẸ OHUN GBOGBO
NINU ODU MẸRINDINLOGUN

Iwe yi kun fun Asọtẹlẹ ati wipe, yio din ọ lowo 'YẸMIWO" ku, nitoripe iwọ na yio le ma da ṣe AYẸWO fun ara rẹ

"KOṢEMANI" ni iwe na, 2/6d pere ni a nta Postage 9d tete lọ ra tirẹ ko to tan

FI OWO RANṢẸ SI -

ẸSAN KOGBOGUN SERVICE

8, Idumagbo Avenue,
LAGOS NIGERIA.
Leti Ọja Jankara L'Eko

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ATI OGO NIPA DYNAMIRE TONIK



ALE-BI-ALE Egbogi Tọ ... amonu tilu ti gbogbo aga ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ d ju fun Akr bara ati Aiẹbida ni iṣẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo

Bi arẹ ara ba nmu ọ, nii gbakugba fun wahala tabi iṣẹ ṣiṣẹ ti o ko le jẹun dara dara, tabi ki o male sun da da de ọkan Isan tabi awọn ṣaa ara rẹ gbogbo ki ṣefun daradara ti Emi Breath inu ko ba kunlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala sise tabi inu awọn ailera gbogbo nyin ti ọjọ ori (age) ba ti kọja ọgbọn ọdun si ader tabi jube lọ mọ d ju pe DYNAMIRE ni egbogi ti o nfẹ lari s ara di tun patapata inu rẹ a j lọ ẹran ara re ti o ti hunjọ yio bi yabo dada Ara rẹ yio gbe kankan ni b kugba yio sao pẹlu igo aba durode o iyẹn d jb

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palm Church Street Lagos
Phone:- 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji)
LAGOS
ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba
NIGERIAN MEDICINE STORES
4, Tinubu Square Lagos

# ‘Ẹ MA FI ỌNA ERU ṢE ẸGBẸ AFẸNIFẸRE’

Eleyi jẹ ohun iyalẹnu lati ri ọrọ kan to jade ninu iwe irohin Imolẹ ti ọjọ kẹtadinlogbọn osu to kọja yi eyiti ọgbẹni Yisa Oseni sọ pe ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ni on iṣe ati pe irọ ni nwọn, npa mọ on pe ẹgbẹ Dẹmọ ni on Iṣe ati po on si jẹ ẹniti o ko ẹgbẹ Dẹmọ wọ ilu Ewu

**Lati Ọwọ I. K. Falohun,**
Akọwe Ẹgbẹ Afẹnifẹre Oshodi

Mo fẹ ki ọgbẹni Oseni lọ mọ daju pe ti o ba fẹ sọ wipe on ti kuro ninu ẹgbẹ Dẹmọ yio ko Iwe si Akowe ẹgbẹ Afẹnifẹre ti ilu Oshodi eyti yio mu iwe na lọ si ile iṣẹ ẹgbẹ na lati fi han gbangba pe otitọ ni Ọgbẹni Oseni kuro ninu ẹgbẹ Dẹmọ.

Eleyi je ohunti o hu si awa ọmọ egbe Afenifere ti ilu Oshodi ati agbegbe re loju pe Ọgbeni Yisa Oseni ki iṣe ọmọ egbe Afenifere bikose wipe ọmọ egbe Demo ni iṣe ati pe ki nwọn ma ṣe le kọlu awọn ile re ni o se sọ pe on ki iṣe Demo.

Ninu awọn ti nwọn ko ẹgbẹ Dẹmọ kọ ilu Ewu pelu Ọgbẹni Oseni ni Ọgbẹni Muse Gbadamọsi, Amusa Gbada ọsi Amalbi Yayọ, Abudu Aṣiru ati Ọgbẹni Sule Igbira ti awọn eniyan si jẹ igi lẹhin ogba ẹgbẹ Ọlọwọ ni ilu Ewu,

Eleyi si jẹ ohunti o buru lati mọ ri ninu awọn ti awọn jẹ Olori tabi Akọwe ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ilu Mushin ti nwọn lọ ngba ọwọ lọwọ awọn ẹgbẹ Dẹmọ ti nwọn ti kọ ile si agbegbe na lati ile ba wọn ma tẹ oruko wọn jade ninu iwe irohin pe nwọn ti di ẹgbẹ Afẹnifẹre eyiti ko ba eto ofin ẹgbẹ Afẹnifẹre mu.

Mo tun kesi awọn Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ẹkun iha Gusu Ikeja lati ṣe iwadi awọn iwa buburu ti awọn enia kan ma nhu nipa pe ki nwọn lọ ma tẹ irohin eke jade loruko ipo ti nwọn wa ni ẹgbẹ Afenifẹre lati le fi ma jẹki awọn ẹgbẹ Dẹmọ ma fi ọgbọn ẹnu sọ pe awọn fi di ẹgbẹ Afenifẹre awọn ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ilu Oshodi ti fi ara mọ pe Ọgbẹni Yisa Oseni ti ọmọ ẹgbẹ Afenifere ti ile Naijiri .


## Ha! Kini eleyi O




OGUN A PA YANMU — YANMU
OLORI ERIN MẸTA NI

Three elephant Brand mosquito coils dara pupọ A ri o dara ju gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ-

O npa yanmuyanmu ninu ile ni kiakia oorun rẹ si dara pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ. Bakan na ni o si tun yara pa ẹyan ati idun

Tete lọ ra packet ogun yanmuyanmu Three elephant Brand coils tire loni, ki o si dan wo, iwọ yio ri bi yio ti ṣe pa gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti iwọ ati awọn ọmọ rẹ yio si sun daradara

Ki ori daju pe ogun yanmuyanmu olori erin mẹta *yi* ni nwọn mu fun ọ

Three elephant mosquito Brand coils yi wa ni ṣọbu ati ile itaja kakiri orilẹ ede yi.

*DISTRIBUTORS*

**Amos GBENLE & BROTHERS**

34, Docemo Street, Lagos
6 & 11 Balogun Street. West
LAGOS


## YE IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 22 Feb 20) Ọjọjọ ti o nṣe ọ ko tẹ mu ire kan wa fun ayafi ki o ṣe apa kitipo ki o ṣoṣuka ki o si gbe eru rẹ fun rarẹ ṣe pẹlẹpẹlẹ nibẹ.

PISCES Feb 30 Mar 20 Ajẹki onjẹ ko dara fun jeki ebi pa ọ daradara ki o to jẹ onjẹ m tan maṣe ara silẹ fun arẹ ayọ n yio gbẹhin ohun kan ti o nro ninu ọkan rẹ.

ARIES Mar 21 April 20 iru ohun ti o de si ọ yi iru rẹ yio tun de si ẹnikan ti o mọ agbara ti o ba ni ni ki o fi ṣe iranlọwọ fun ẹniken ti iru rẹ ba de si.

TAURUS April 21 May 20 Iyemeji rẹ ti o o nṣe yio ṣi kuro kiki ki o si sa gbe ọkan rẹ kuro nibẹ ṣugbọn ki o ṣọra ki o ma ba gbọn owo danu.

GEMINI May 21 June 21 Ṣọra ki o maṣe pọn ararẹ ni aponpo nigbati a ba dan ọ wo ma e da imọran kan ti ko nilari.

CANCER June 22 July 22 Ṣe pẹlẹpẹlẹ ki o maṣe k wadu wadu ṣe ohun kohun inu ọrọ ti o ba jẹ mọ ti owo

LEO (July 23 Aug 23) Iwọ yio ri itẹlọrun lọna kọna ti o ba gba loni, ohun kan ti o ngber lati ṣe yio bo si ṣiṣe, ṣugbọn maṣe jẹki igberaga rẹ papọju,

VIRGO (Aug 23 Sept 23) Gẹgẹbi o ti ṣe lana, tun ọrọ na ro, iẹjẹ pẹlu suru, nigbẹhin ire rẹ yio jẹ tirẹ.

LIBRA (Sept 24 Oct 23) Mu ọkan kuro nibi amodi ti o ti nṣe roy roy rẹ, Iwọ yio jegbadun lati awọn, ẹrẹ rẹ loni ṣugbọn ki o wo gẹgẹbi imọ yio tiṣe na owo

SCORPIO Octo 24 Nov 22 Gbogbo irawọ ọrun lo mba ọ jọ ayọ lati mu ohun ti o nro lọkan rẹ ṣẹ kisi wi pe ki o je oloto ati Olododo

SAGITTARIUS Nov 23 Dec 21 Ayọ da titun kan yio fi ara han ni iwaju rẹ ki o maṣe se royi royi ọkan

CAPRICORN Dec 22 Jan 21 Maṣe se ara ọkan si ipa ti o nfẹ ki o maṣ se jẹ awọn ti ogbon ati etekenda fa ọ lọ sinu inawo rẹpẹtẹ kan

## Ẹ Ma a Polowo Oja
## Nyin Sinu Irohin Imọlẹ

# Agba Ilu Awẹ O Di Ọwọ Nyin O

Lati Ọwọ J. Ọlu Akintunde, Eko

Mo bẹ ẹnyin agbalagba ilu Awẹ lati tun ilu Awẹ ṣe, ati gbogbo awọn olowo ati ọlọrọ Awẹ bakanna pẹlu bakanna pẹlu bakanna mo bẹ gbogbo ẹnyin agba ilu Awẹ l. ti jawọ kuro ninu ọbẹ apọn ti ko yọ ki ẹ gbe omi ila kana

Orukọ ilu Awẹ ga ju bi ti a ṣe npe lọ nibikibi ilẹ Naiji ria ati papa sisọ ni agbaiye nitori idi eyi mo bẹ gbogbo ẹnyin Agbagba Awẹ ki ẹ ma jẹki ọrọ na bajẹ lọwọ nyin o. Oluwa ko ni ba ilu Awẹ jẹ o, amin

Ẹnyin agba ẹ ṣe ki o yẹ Awẹ O, b ọrọ ilu Awẹ na si ti nlọ ko ye awa ọdọ ọmọ ibilẹ Awẹ na o nitoripe baba ko gbọdọ sọ pe o di ọwọ ọmọ on ti o nbẹ lọrun, ọrọ na wa di ọwọ ẹnyin agba ẹ ṣe ki o yẹ wa o. Bawo ni awa ọdọ yio ba ṣe mọn nigbati o jẹ wipe ẹnyin Agba ilu Awẹ ko fi ọna han wa ?

Ina monamona de ile iwe giga ti ilu Awẹ (Awe High School) ti o jẹ pe ko si ju iwọn ọgọrun (100 yards) ọpọlọpọ si ilu Kaka ki e gbe ina na gba igboro ilu Awẹ lọ ṣebi ọna ibomiran ni ẹ ki nwọn gbe egba ọrọ nu wa di ọmọ ẹnyin agba ilu Awẹ bẹni nwọn fi opo ina tan wi jẹ ni ilu Awẹ ba kanna lajẹ pe ẹ ti wọn mo lẹ fun lilo.

Awẹ jẹ ilu kan ti Oluwa ti da sori oke ti ko si le fi ara rẹ pamọ fun ẹnikẹni ki o ma leri Nipa Ọlaju Awẹ laju ju ati gbogbo awọn agbegbe rẹ lo bẹ na si tun ni mọ ẹkọ nwọn ko gbọdọ sọ pe ti Awẹ bawo ni

Awẹ jẹ ilu ti o kere ju gbọn o kun fun wara ati oyin awa ko ro gbogbo e'e yi awa mo bi a o ti ṣe yọ Ọba Ọladokun ti ilu Awẹ kuro oye rẹ Agba ti wa ilu ki o i ẹm tiiun wọ bi ẹ ba si ni ki o wọ laju nyin iyoku wa ku si ọwọ nyin

Ọrọ ba ko ni baje lọwo ọdọ ti ọrọ ba bajẹ agba ni ki ẹ pe o Ẹnikẹni ti o ba ni un yio ba Awẹ jẹ Oluwa yio ba ti oluwarẹ jẹ o Ilẹ Awẹ Orisa ronu Awẹ ati omi sogidi Awẹ ko ni jẹki ti Oluwa rẹ toro Amin Abọ ọrọ ni a nsọ fun ọmọ luwabi ti o ba de inu rẹ a dodidi Ẹnyin Ọlogbon ati oloye agba ilu Awẹ e gbe yẹwo o

# Asọbade Orire Are Bọọlu

## First Division

| | | | |
|---|---|---|---|
| Arsenal | v | Aston Villa | x |
| Burnley | v | Tottenham | x |
| Chelsea | v | Liverpool | 2 |
| Everton | v | Sunderland | 1 |
| Manchester Utd | v | West H. | 1 |
| Newcastle | v | Leeds | 2 |
| Northampton | v | Blackpool | 2 |
| Nottingham F | v | Leicestar | 2 |
| Sheffield W. | v | Blackburn | x |
| Stoke | v | Fulham | 1 |
| West Brom | v | Sheffiţld U | 1 |

## Second Division

| | | | |
|---|---|---|---|
| Birmingham | v | Man C. | x |
| Bolton | v | Woves | 2 |
| Charlton | v | Soutuamdton | 2 |
| Crystal P | v | Caraiff | x |
| Huddersfield | v | Carlisle | 1 |
| Ipswich | v | Rotherham | x |
| Leyton O | v | Bristol C | 2 |
| Middlesbro | v | Conventry | x |
| Plymonth | v | Bury | 1 |
| Portmouth | u | Norwich | - |
| Preston | v | Derby | - |

## Scottish Div 1

| | |
|---|---|
| Aberdeen v Rangers | 2 |
| Clyde v Falkirk | 1 |
| Dundee v Dunfermline | 2 |
| Hamilton v St. Johnstone | x |
| Hibernian v Dundee U | x |
| Kilmarnock v Hearts | 1 |
| Morton v Motherwell | x |
| Partick v Stirling | x |
| St Mirren v Celtic | 2 |

## Scottish Div 11

| | |
|---|---|
| Airdrie v Brechin | 1 |
| Cowdenbeath v Alloa | 1 |
| Dumbarton v Forfar | 1 |
| East Stirling v East Fife | x |
| Montrose v Albion | x |
| Queen's Pk. v Q of Sth | x |
| Raith v Berwick | 1 |
| Stenhousemuir v Ayr | 2 |
| Stranraer v Third Lanaak | x |

TREBLE CHANCE
12 Draws

Aasenal, Sheffield, Wednesday, Birmingham, Crystal Palace Ipswich, Presten, Aldeshot, Darling ton Shrea; Hamilton Montrose Yueens Park

AWAYS (12)

Lede Leicester Wolf Southam- Bristol C'ty Grimsby Hull Swindon Milwall Watford Rangers.

HOME 15

Everton, Man Utd, Stoke, Huddersffield, Plymouth, Portsmouth Bournemouth Chester Crewe Hartlepools, Port Vale Rochdale Clyde Kilmaknock Airdrie

THREE DRAWS 6)

Birmingham Preston, Shrewsbury Quee's Park, Arsenal Aldershol.

## F. A. Cup Second Round

| | | | |
|---|---|---|---|
| Aldershot | v | Walsall | x |
| Barnsley | v | Crimsby | 2 |
| Bournemouth | v | Bath | 1 |
| Brighton | v | Bedford | 1 |
| Chester | v | Wigan | 1 |
| Corby | v | Remfora | x |
| Creve | v | South Shields | 1 |
| Darlington | v | Oldham | x |
| Gateshead | v | Hull | 2 |
| Grantham | v | Swindon | 2 |
| Hartlepools | v | Wrexham | 1 |
| Hereford | v | Millwall | 2 |
| Port Vale | v | Darford | 1 |
| Q. P. R | v | Guildford | 1 |
| Readings | v | Brentford | 2 |
| Rochdale | v | Altrincham | 1 |
| Shrewsbury | v | Peterbro | x |
| Southend | v | Watford | 2 |
| Southport | v | Stockport | 2 |
| Wimbledon | v | Folkstone | 1 |


## EGBOGI JEDIJEDI

BERE FUN EGBOGI

"CYCLEVEN"

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jẹdijẹdi rẹ gbe wa lara rẹ o si nyọ ọ lenu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu" tabi iho idi enia ibiti a ma ngbe ṣe igbọnsẹ. Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun Ọkunrin ti o si lagbara lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri ode nisisiyi ti wọn ama polowo wọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya ta le ri mẹwa ninu ogọrun ti o le ṣe iwosan arun yi daradara. Awọn ẹlomiran lere wipeboya bi awọn ba lọ si ile Dokita lati lo ke eyiti o ba nyo jade lati omusu kuro ni, pa bẹ awon o bo lowo rẹ palapata

Ṣugbọn awa ko ro bẹ rara: Lẹnin odun die iyonu rẹ yio si tun ma bẹrẹ bakanna, Orisirişi Jẹdijẹdi ni o wa ekini ti o bẹrẹ nipa aiko ma ṣe igbonse dede tabi lojojumo, elomiran nipa ijoko ni ojukanna selu lojojumọ tabi gigun keke ylogere (Basikulu) pupo elomiran ewe nipa jije Şuga tabi oniruru ohun adidun pupo ju. Jedijedi orişirişi ni o wa ewo ni tirẹ? Bi o ba nyo jade ninu oiusu tabi ti o ba nmu wa lẹhin igbọnsẹ tabi to ba nyo ti o bi ṣe igbonsẹ tan ni, tabi ti o nno ni musu ni eyikeyi ti o bara bere egboki "CYCLOVEN" ti awon Oyinbo Jamani lere wa idi rẹ ko ki o si danwo o işi meta ni o da u wipe iwo yio bo lowo Je i patapata alafia y'o de si ekeji re ko si ninu gbogbo egbogi si igboro ilu Naijiria Bere re ni:—

Waterloo Medecine Store
8, Palm Church Streer Lagos.
Phone 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji
LAGOS

ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, Tinubu Square Lagos

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

No 1,576 FRIDAY DECEMBER 3, 1965 (2D


## Omo Ẹgbẹ UPGA Mẹrin Jare Ẹjọ

OYO:- Ni ọjọ ọjọ Ru ti iṣe ọjọ kini oṣu yi ni Adajọ agba ti ile ẹjọ ti Ijọba ibi'ẹ ilu Ọyọ ti paṣe pe ki awọn ọmọ ẹgbẹ itesiwaju (UPGA) merin ti ilu Igbetti leba Ọyọ ma lọ ni ayọ ati alafia lori ẹsun ti Ijọba mba wọn se pe awon ọmọ egbẹ UPGA na ko awọn ohun ọṣẹ lọwọ ati pe nwọn tun fẹ da rogbodiyan silẹ larin ilu.

Ninu ẹjọ ti nwọn ba awọn ọmo ẹgbẹ UPGA merin na ṣe ni Adajọ agba na ti ṣe alaye ninu idajọ rẹ pe ko si ẹsun kan to fi idi mule eyiti o fi daju pe awọn enia na jẹbi ẹsun ti nwọn fi kan wọn.

Awọn ọmọ ẹgbẹ UPGA merin na ni Akabi Akọwe, Tijani Arẹmu Jacob Babatunde ati Durodọla Alamu.

Ninu ọrọ Agbẹjọro fun awọn ọmọ ẹgbẹ UPGA na ni Ọgbẹni Olu, Oke owọ ti ṣe alaye pe awon enia na ko ni ẹjọ kankan lati ro niwaju ile ẹjọ na.

Ṣugbọn ile ẹjọ na tun ṣe alaye pe Luku Akano ti nwọn mu pẹlu awọn enia na ni ẹjọ lati jẹ niwaju Adajọ ile ẹjọ na.

Ninu ọrọ ọlọpa to ba awọn enia ṣe ẹjọ ni o ti ṣẹ alaye awon enia na lo kọlu Adakẹ Agbekẹ ati Ọgbẹni Popoọla ati pe awọn enia si na awọn enia pẹlu ohun ọṣẹ eyiti awọn enia si fi ara gbọgbẹ pupọ ile ẹjọ yio ma ba gbigbọ ẹjọ na lọ.

# AWỌN OLUKỌ (TIṢA) FẸ BINU DA IṢẸ SILẸ

EKO:- Ninu ipade pajawiri kan ti awọn Aṣoju Igbimo awọn oluko ilẹ Najiria ṣe ni ilu Eko ni ọjọ Abameta ti iṣe ọjọ ketadinlọgbọn oṣu to kọja lọ yi ni awọn aṣoju Igbimọ awọn olukọ na ti ṣe ipinnu pe ti Apapọ Ijọba ilẹ Naijiria ko ba tete da awọn lohun lori ohunti awọn nbere lọwọ wọn pe awon yio kesi gbogbo awọn olukọ ja kejado ilẹ Naijiria lati binu da iṣẹ wọn silẹ ati pe ki wọn maṣe kọ awọn ọmọ ilẹ ẹkọ ni nkankan.

Ninu ohunti awọn Igbimọ awọn ẹgbẹ olukọ na jiroro le lori ohunti wọn yio ṣe nibi ipade wọn ti wọn ṣe lojo na ni eto pe awon olukọ ni jakejado ilẹ Najiria yio binu da iṣẹ silẹ ni ohun ti o jẹ pataki ninu ọrọ ti awon oluko na jiroro lelori.

Awon igbimo ẹgbẹ oluko na tun ṣe ninu ipade ti won ṣe ni ojo na pe awon ko fi ara mo eto ti apapo ijoba ṣe nipa ẹkunwo owo oṣu eyiti awọn Igbimọ awon oluko ati awon aṣoju fun apapọ Ijọba ba wọnṣe lori eto ẹkunwo owo osu eyiti awon Igbimọ na tun ṣe alaye lelori pe ki ise ohunti awon ba apapọ ijoba ṣe eto le lorini nipa owo ti se fun awọn oluko ilẹ Naijiria.

Awọn igbimọ ẹgbẹ olukọ na tun ṣe alaye ninu ọrọ wọn pe awon si fi ara mọ ikede ti o jade ninu awọn iwe irohin lori eto ti awọn aṣoju igbimọ to nṣe eto lori abayori eto ti awọn Aṣoju awọn Olukọ ati ti apapọ Ijọba eyiti a npe ni (NCNC) awọn Igbimo ẹgbẹ olukọ na tun ṣe alaye pe awon dupẹ pupo lowo awon Aṣoju na lori eto ti nwọn ṣe nipa ẹkunwo owo oṣu fun awọn Oluko ni jakejado ilẹ Naijiria.

Ninu awon ohunti awon Igbimo ẹgbẹ awon olukoilẹ Naijiria jiroro le lori niwon yi:-

Awon Igbimo awon oluko na tun sẹ alaye pe apupo ijoba Naijiria ni lati fi ise si eto ti awon Igbimọ awon oluko ati awon asoju Ijọba lori eto ẹkunwo owo oṣu fun awon olukọ ati pe gbogbo awọn Ijọba Ipinlẹ mẹrẹrin to wa ni ilẹ Naijiria ni o ni lati tẹle eto ti awọn Igbimọ NJNC ba ṣe silẹ ati pe ki awọn Igbimọ ile ẹkọ ti o jẹ ti Ijọba ibilẹ bakanna ni lati fi ara mọ ohunti awọn Igbimọ NJNC ba ti ṣe lori ẹkunwo awo oṣu fun awọn olukọ ni jakejado ilẹ Naijiria.

Awọn Igbimọ awọn olukọ na ti se alaye ninu ọrọ wọn pe gbogbo awọn Ijọba to wa ni awọn Ipinlẹ Naijiria ati awọn Igbimọ eto ẹkọ fun Ijọba Ibilẹ ni jakejado ilẹ Naijiria ni nwọn ni lati tẹle eto ti owa ninu Iwe ade hun apa kẹrindinlọgbọn ati ketadinlogbọn ti eto eyiti awọn Igbimọ NJNC ti gbe jade ninu eto ekun owoosu fun awọn Olukọ

Awọn Igbimọ ẹgbẹ olukọ na tun ṣe alaye pe awọn kọ eto ti apapọ Ijọba Naijiria ṣe lori eto ẹkun owo osu eyiti apapọ Ijọba gbe jade ati pe nwọn sifi ara mọ Igbimọ NJNC pe iye owo ti nwon yio ma san fun awọn olukọ ninu iwe ti abayọri ẹkunwo owo osu awọn olukọ apa kerinlel dota karun dinlọgọta kẹtadinlogọta ke dinlogota ati apa kọkandin logota ti iwe eto ẹkunwo owo osu eyiti abayọri rẹ ja de bayi pe

Awon oluko ti nwon yio ma ṣiṣẹ ninu Ile ẹkọ giga eyiti o ni imọ Ijinlẹ lori to ẹko ni uwou yio fi poun mẹrinleni ẹgbẹrin (£804) lọdu kan bẹrẹ owo osu rẹ fun Awọn oluko ti nwọn je oni po kini yio ma gba ẹgbon lenirinwo poun £430 lodun kan eyiti yio gba titi de igb le poun merindin ọgofa po ou £1,116

Ako ti mọ asiko ti awon oluko na yio da iṣẹ silẹ ati pe bi nwon ba tiṣẹ orona si eo ma gbo ninu we yi

## Iatl Oju Ewe Kini

aja ilu yika Ipinlẹ Iwọ Orun ni wipe, awọn ko dibo fun ẹgbẹ Dẹmo, ṣugbọn nigbati abayọri ibo jade, awọn akowe Ibo sọ wipe ẹgbẹ Dẹmọ lo wọle

Ọkan ninu awọn enia na ṣe alaye fun oniwe Irohin wa ni Mushin ni irọlẹ ana wipe nigbati awọn ko dibo fun ẹgbẹ Dẹmọ, bawo ni nwọn ti ṣe le wọle?

'Ko si ẹniti o nṣe ẹgbẹ Dẹmọ yika gbogbo Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria, ko da awon ti nwọn nsọ wipe awọn nṣe, ẹgbẹ Dẹmọ oju aiye ni nwọn nṣe, nwọn nfi ẹnu ṣe Dẹmọ ṣugbọn ninu ọkan wọn UPGA ni nwọn nse,

Nitori idi eyi ni awọn enia na ṣe binu ti nwọn si pinnu ni ọkan wọn wipe ẹniti awọn nfẹ ni ori aga akoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ni awọn ti dibo fun awọn na ni nwọn si wọle pẹlu.

Awọn ko wa fẹ ki ẹnikan fi ipa jẹ Ijọba le awọn lori ẹniti o wa awọn ni awọn ti dibo fun awọn na ni awọn si nfẹ ni ori aga akoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun pẹlu,

Mọto ti ẹ nwo aworan rẹ ninu iwe eke yi jẹ ti KIA-KIA Bọọsi kan ti nwọn da ina sun. Bi awọn ti da Ina si Bọọsi na tan ni awọn ọlọpa ti sare kesi awọn panapana ti nwọn si lọ pa ina na, ṣugbọn ki panapana to de mọto ti jona tan.


E Ma a Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ

E Ma a Polowo Oja Nyin Sinu Irohin Imọlẹ



Printed & Published by Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street, Lagos Phone 21985
Editor: [illegible] 15 [illegible]